**In Memory**

IN REMEMBERANCE of my Dearly beloved Husband and Father (ALIAS-ARADAN) who slept in the Lord November 15th 1960. Gone but not forgotten by:
JUDITH INUOLA SHIWOKU & SISTERS

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

2 Advance Apprentices 2 Apprentice Printers Apply in Person to:-
TWIN PRINTING PRESS 32 TOKUNBOH STREET, LAGOS NIGERIA.

VOL. V No. 305 MONDAY NOVEMBER 20 — NOVEMBER 26 1961 KỌBỌ MEJI (2)

# OBINRIN KAN GUN EKEJI RẸ LỌBẸ NITORI ỌKUNRIN

EPẸ:- ROGBODIYAN NA ṢELẸ NILU ẸPẸ LARIN AWỌN OBINRIN KARUA MEJI NITORI ỌKUNRIN KAN TI O WA WỌN WA. EKINI SỌ WIPE, ŁỌDỌ ON NI ỌKUNRIN WA, KO SI NṢE ONI TABI ANA LO TI NWA SI ỌDỌ ON BẸ.

Obinrin keji fi aake kọri wipe, rara! on ko tilẹ gba wipe ọkunrin na mọ ọ ri, on pelu rẹ ti mọ ara wọn, Onibara on lo si nṣe pẹlu. Ẹnikini kọ, ẹnikeji taku wọnle, eyiti a nwi yi npẹ awọn mejeji ṣolu ara wọn.

Ekini gbe ọbẹ o fi le ekeji ti o njẹ Safiatu Kano, nigbati oju rẹ ti ranko, nitori ọkunrin ti o tọwọn wa na jẹ giripa, o si kato, ni kia mọsa, nwọn gbe digba digba o dile alaisan o mbẹ nisisiyi ninu rọju jẹ ati rọju mu.

Awọn Ọlọpa sọ wipe, ọrọ na ṣẹlẹ nitori Ọkunrin kan ti o kato, ti o wa ọkan ninu awọn obinrin mejeji na wa, bi ere, bi ere, nwọn fa ọrọ na, de ipo ti awọn mejeji fi wọya idimu. Bi eyiti o ni agbara ju ninu awọn onija mejeji yi ti gbe ekeji rapata, o digbẹ nilẹ, eyi ni Safiatu Kano, ti o da ẹnikeji.

A gbọ wipe, nṣe ni awọn Ọkunrin to wa nibẹ ho ge e e oju si ti i, lo ba yọ ọbẹ alafẹfẹ kan, lo gbe le Safiatu ẹpọn ẹjẹ ba yọ. Ọdaran na wa ni ikawọ awọn Ọlọpa.

## Ogbeni Olarewaiu lo se abewo. Agbegbe ile Sokoto

ṢOKOTO:- Agbọ wipe ninu irin ajo ti Ọgbẹni M. A. Ọlanrewaju rin lọ si Oke-Ọya nigbati o de ilu kan ti nwọn npe ni agbegbe Sardauna, awọn ara ilu na si yẹ e si gidigidi, nwọn si se aponle rẹ ninu iwe ẹyẹ ti nwọn fi ki kabọ. Ọgbẹni Ọlanrewaju ti ṣe alamojuto awọn Ọlọpa sọ wipe, Ijọba Eko ati Ijọba Hausa, ko jafara nipa mimu ogiri fun alafia ati idẹra awọn ara agbegbe ilu Sardauna.

Awọn ara ilu na sọ fun Ọgbẹni M. A. Ọlanrewaju wipe, awọn lero pe awọn ara Naijiria nikan ko le ma jẹ anfani idẹra ati ilọsiwaju ti Ominira mu wa fun wọn pẹlupẹlu awọn fi ara mọ ọna ti awọn Ọlọpa fi nṣe eto itọju ofin ilu. Inu awọn yio dun gidigidi nilu Chamba bi Ọlanrewaju ba le ṣe iranlọwọ ki awọn ọmọ wọn ti o ba ti ka iwe mẹfa ninu ile ẹkọ alakọbẹrẹ ma wọ iṣẹ Ọlọpa. Lẹhin eyi, ni Ọgbẹni D. J. M. Muffet ti iṣe Ajẹlẹ agba fun agbegbe ilu Chamba lọna ilu Sardauna ba se ase rẹpẹtẹ lati fi yẹ Ọgbẹni Ọlanrewaju si.

**Wanted**

An experience Yoruba Editor. Apply in Persons to:-
IROHIN IMỌLẸ
16, Bamgbose Street, Lagos.

## Dokita Nkruma pelu Oba Obinrin Ile Gesi



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni Ọba Obinrin Gẹsi Queen Elisabeth Keji nigbati o lọ bẹ ilẹ Ghana na wo Lọwọ osi ni Ọgbẹni Dọkita Kwame Nkruma tise Baba ẹgbẹ ilẹ Ghana duro si, ni arin meji ni Ọba Obinrin duro, ẹniti o si duro ni ọwọ ọtun ni Ọgbẹni Kweku Busuẹ ti o jẹ ọkan ninu awọn ti o lọ pade ọba Obinrin.

Wo aworan gbogbo ariya ti nwọn ṣẹ fun ati gbogbo awọn enia ti o lọ pade rẹ loju ewe keji ati keje.

# Ọrọ Olotu

## Agbajo owo ni a fi nso aiya

Awa Oniwe Irohin Imọlẹ ko ni fi ẹnyin Onkawe wa silẹ lojo kan lai ko jẹ wipe a o ma tubọ gba nyin ni iyanju nipa iwa okunkun ti ẹnikọkan yin ma nhu. A fẹ ki olukuluku yin mọ daju pe, ohunkohun ti a ba ṣe ni ikọkọ, Imọlẹ rẹ kedere ni niwaju Ọlọrun Ẹlẹda wa ti o da Ọrun on Aiye ati gbogbo awa ti a si wa ninu rẹ jake-jado gbogbo Agbaiye.

Pupọ ninu yin lo jẹ wipe, bi Ọlọrun ba gbe yin de aye kan laiye yi, ti ẹ ba gẹsin, nṣe ni ẹ o ma ṣogakọ nu, pupọ igba ni a si ma fi ibi ṣu olore ,eyi tilẹ pọlarin awa enia ilẹ Naijiria lode o n i, ohun na lo fi mu ore su nise.

Afẹ ki gbogbo ẹnyin enia mọ daju pe ore lo pe ika ko pe, bi o ba ṣe ore lo mọ ṣe j o w ọ mura si, ẹsan mbọ, bi o ba si jẹ ika lo mọ ṣe mura si, ẹsan ko gbogun, ore ti a ṣe fun adẹ ko gbe, bo pẹ titi omitoro rẹ a kan si ni lẹnu. Papa lasiko yi, ohun pataki ti a le bi ara wa lere ni po, kini o yẹ ki a ṣe nigbati Ominira ti di ti wa, ti o si tun ti pe ọdun kan yi? ohun ti awa Oniwe Irohin Imọlẹ lero pe o yẹ ki a mura si lati ma ṣe ni pe, ki a fi iwa I k a, Wọbiya Imọ ti ara ẹni nikan ati gbogbo iwa okunkun tabi eyiti ko yẹ ọmọ enia ni sise silẹ, ki a m u r a si ore ni ṣiṣe, ki a si ma wa ilọsiwaju fun Ilu wa yi.

Ni aye kaye tabi ipokipo ti a ba wa, ki a ma ri pe a nṣe otitọ, ati ilọsiwaju fun Ilu wa Naijiria, bi o ba wa ni ipo pataki ki o ma fi ṣe ore fun awọn ọmọ abẹ rẹ, ma ṣe lo ipo na ni ilokulo. Ohun ti a fẹ ki o da ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ loju nipe, ti a ko ba di amuṣe giri, ki a mura ki a le gbe Orilẹ ede wa yọ ninu gbogbo Orilẹ-ede Agbaiye, ki a jawọ k u r o ninu iwa Ika, Apamọ, ki a mura si ore ni ṣiṣe, ki a ma ran awọn Oṣelu wa lọwọ lọ na kọna, laiko ṣe awọn nkan wọnyi atubọtan Ilu wa ko le dara, nitoripe ododo lo ngbe Ilu ga.

## Akoni obinrin ni Ile Ghana



Obinrin ti a nwo yi jẹ, ara awọn Akọni obinrin ninu awọn Aganyin, bi Ọgbẹri enia ba kọkọ ri awọn ti a nwo aworan rẹ yi, yio dabi ẹnipe gbogbo ori wọn lo hu koriko, iru eyiti awọn Gẹsi ṣe nigba ogun ilẹ Boma (Camoflage) lara aṣọ Ankara ti o wọ si ọrun ni a ya aworan Nkrumah ati Iyawo rẹ, ara ilẹ Egypt si.

## Dokita Asikiwe nyo ayo Ajodun meji papo nilu Eko

Dr. Nnamdi Asikiwe ti iṣe Ọlọla gomina Agba fun ilẹ Naijiria fi o nṣe ajọdun meji papọ ni ọjọ 16th. oṣu November 1961. Alakọkọ ninu awọn ajọdun na ni pe Ọlọla Zik goke agba, o di ẹni ọdun mẹtadilọgọta (57 yrs.) ati ekeji ninu ajọdun na ni wipe, odi ọdun kan gbako ti Ọlọla na gun ori oye gomina Agba (governor general)



Dr. NNAMDI ASIKIWE ATI IYAWO RẸ

Lọwọ-lọwọ nisisiyi, oporo iwe ikini lo ntọwọ lọ si ilu Nsukka nibiti gomina gbe fi ṣe ibi isimi rẹ Ijọba koiti ṣe awọn iwe Ikini na ni gbayawu tobẹ ti awọn oniwe irohin lefi mọ, ayafi eyiti Oloye Okotie-Ẹbọh kọ ti o fi ki gomina Agba.

Nigbati Ọlọla gomina Agba fi nṣe ajọdun ọdun kẹtadilọgọta, o fi ẹgbẹrgbẹrun mẹta ṣe italọrẹ fun awọn ara ilẹ Naijiria wipe, ki awọn fi owo na ṣe owo ẹkọ ọlọfẹ fun Ọmọ ilẹ Naijiria ti o ba yẹ lati lọ kọ Ẹkọ Giga ninu University of Naijiria. Ki awọn si fi £5, 300 ra iwe titun si ile ẹkọ na.

ADVERT 209.

**Inland Waterways Departments**

NOTICE NO. 9/1961

It is promulgated for general information that the Lagos/Warri Creek Mail Service will not call at Torofoni after the 15th. November, 1961, due to insufficient depth of water.

(Sgd) E. A. AILERU,
ACTING DIRECTOR,
INLAND WATERWAYS DEPARTMENT

## Kini O mo Ni pa Ile Naijiria?

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TI O WA LOJU EWE KETA?

(1) Opopo (Broad Street) (2) Daily Express
(3) Olawale Said. (4) Igbagbọ ati Ododo,
(5) Bicycle ati Pirate. (6) Ọgbẹni Dr Prasad
(7), 1744, (8), 1886
(9) Iọdun 1791 (10) Ọlọla Ọbaiẹmi Awolọwọ
(11) 1744

# Esi Oro Omo Aridegbaju

Lati Qwọ:— SISA EKUN TOJO KỌ.

Ọmọ Aridegbaju tun fẹ nu kan Ologbe Alhaji Akọshile lori eyi, emi ko ni nkankan sọ, iwọ pẹlu ara ọrun ni ẹlẹjọ. Ṣugbọn mo fẹ fi han gbogbo onkawe Irohin Imole pe emi ti mo nkọwe yi jẹ ọkan ninu awọn Imọlẹ (Muslims) Ilu Oro ati lati fi han wipe ọrọ ati mo nre suni ṣe ni Ọmọ Aridegbaju nba mbọ nitoripe koni sai ranti iru itanlọwọ owo nbiribi ti awọn arakunrin wa Onigbagbọ (Christians) yi ma nṣe lọdọdun ninu Ikore wa lati le ri owo kojọ fun ilọ si wa ju Ilewe Muslims ati ti Mọsalasi Jimọ titun ti a nkọ ni Ilu Oro.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJO.


## Ha! Eti Re Melo?

Ki Ibise tabi awọn Aladugbo re ni asiko Ọdun Keresimẹsi ti o de tan yi ninu aye ti a o fi silẹ fun ẹnikẹni ti o ba fẹ Polowo Ọja rẹ ni gbanjo fun ti Ọdun Keresimẹsi ninu Iwe:-

# IROHIN IMOLE

ti ọjọ Kejidilogun ọṣu December 1961 silẹ kan fun Eyọ Ọrọ Marun pere (1/- For Five Words)

Ti o ba fẹ ṣe eyi wa, tabi ki o kọ ohun ti o fẹ sọwọ ranṣẹ pẹlu iye owo rẹ si:-

ALAKOSO IPOLOWO OJA
16, BAMGBOSE STREET LAGOS
Phone 21985. Tabi ki o pe wa lori Ero Isọro.



## MOGBAYI COUGH MIXTURE




Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ orisirisi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde beni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu. E ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ. Igo kan rẹ jẹ 2/6d' atapọ rẹ jẹ 24/-.)

LILO RE:-

Ọmọ oṣu mẹta...Idaji ṣibi tea kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oṣu mẹta si mejila:- Ṣibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa:- Ṣibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba ............Ṣibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

6, Balogun Street West
Lagos, Nigeria.
Phone 22515.

34, Docemo Street,
Lagos,
Phone 24247.


# ASEJU BABA ASETE

Lati ọwọ:- Eni Qwọ Ọmọ Aridegbaju. Oke-ọla oro.

Mọki gbogbo ẹnyin Oluteti silẹ gbọ ọrọ mi ti ọsẹ yi, papa julọ awọn Olukawe Irohin Imọlẹ: Ọlọrun koni gba iskaye yin, Ọgbọn yin yio ma lọ siwaju, akọkọ ọrọ mi ni pe emi ko ba fun ọgbẹni Sisa ẹkun tojo kọ lesi ọrọ rẹ lọsẹ yi, ṣugbọn ara kunrin na koiti pari ọrọ rẹ dele, Iyẹn lo fa ti esi ko fi jade lati ọdọ mi, mo fẹ ki gbogbo enia mọ pe ki ṣe gbogbo enia toba sọ si ọrọ mi la nfun lesi, eyiti ọrọ rẹ ba yẹ fun esi, a o fun lesi eyiti ọrọ rẹ ba ku diẹ ki a to a ko ni fun lesi, nitoripe ọrọ kiṣe asonu, ninu ẹran ni ti njade kin to fun Ọgbẹni Sisa ẹkun tojo kọ yi lesi ọrọ rẹ, ibere kan yio kọkọ wa na, Ibere na lọ bayi pe:- (1) Ki ọgbẹni yi laye araiye dada nipa oruko rẹ yi, boya asijẹ ni oruko yi jẹ fun ọgbẹni yi a komọ, Sisa Ẹkun ni tabi yiyọ ẹkun? nigbati o sọ pe ẹkun nsa ti ko si ki ṣe tojo. Kini ẹkun wa sa fun? Nitori idi eyi iwọ ọgbẹni yi kio ronu dada ki o to bẹ sodo, ti iwọ ko ba mọwẹ ki o ma ṣe bẹ ṣodo ki o ma ba gbe ọ lo, ohun ti ẹlẹsẹ meji fa ti, ti kori fa to ngbọn lori iduro, ki ẹlẹsẹ kan to wa sọ pe on ma fa tan gbogbo ẹnyin ọlọgbọn ẹ ko ri pe irọ lo npa.

Ọrọ mi ti ọsẹ yi dorikodori odo ri alaṣeju baba aṣetẹ aṣeju nlọ si nrin ajo wọn bi lere pe ọjọ wo ni yio de o ni o di ọjọ ti on ba tẹ ki on to de, bẹ gẹgẹ ni ọrọ ẹnyin Ọtun Oro ri gan, Kini kan ni mofẹ kiẹ mọ dada, kiṣe wipe monbu yin, emi ko bu yin rara, papa julọ ọrọ yin ndun mi, ki Ọlọrun ọba alanu ki o yi yin pada si dada, ki Oluwa fi dada parọ aidara yin. Iyẹn gan ni mo nfẹ, nitori kosi bi baba ti ma bimọ to ti yio sọ pe ki ọkan jẹ were ọmọ. Ẹnyin Olukawe mi gbogbo o dun mọ mi pe ẹ ti ngbọ kun mu kun mu nipa Ọja Oro yi; o to ọjọ diẹ sẹhin, mo si fẹ ki o ye gbogbo yin daju pe ọja na, ọja baba gbogbo wa ni ọja na.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJO

# Dr. Omololu nilu Oyinbo



Eniti a nwo yi ni Dokita Ọmọlolu ti iṣe ọkan ninu awọn aṣoju ilẹ Nigeria nilu Oyinbo on lo de fila onidẹ, ẹniti o si mba sọrọ ni Ọgbẹni M. M. Ahmed, ọkan ninu awọn olotu, United Nation Organisation.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Bi Olorun ko Pani, enia ko le Pani.

LATI ỌWỌ:- AKIBU FOHUNỌLA
NO. 85, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE.

Ni ìgba atijọ, awọn ọkunrin meji wa ni ilu kan, orukọ ekini a ma jẹ B'ọlorunkopani-Ọbakolepani, ekeji si tun njẹ B'ọbakopani-Ọlọrunkolepani, Ọba kan wa ni ilu na, nigbati o gbọ orukọ awọn ọkunrin meji yi o si ransẹ pe awọn mejeji.

Nigbati nwọn de ọdọ rẹ, o bere orukọ wọn, ekini ni on ma jẹ B'ọlorunkopani-Ọbakolepani, ekeji ni on a ma jẹ B'ọbakopani-Ọlọrunkolepani. Nigbati Ọba yi gbọ orukọ awọn ọkunrin wọnyi tan, Ọba ba wọle ni o ba fun eyiti o sọ wipe B'ọlọrun ko pani ni aṣọ funfun, o si fi aṣọ dudu fun B'ọbakopani, o si ran awọn mejeji j a d e, ṣugbọn ki o to ran wọn jade, o ti ran Tafa-tafa kan lati lọ sapamọ de wọn ninu igbo wipe bi awọn ọkunrin mejeji yi ba mbọ, ki o ta ọfa lu alaṣọ funfun, ki o si pa ni apa tan.

Nigbati awọn ọkunrin wọnyi jade kuro nile Ọba, B'ọbakopani bẹrẹ si sọ wipe, aṣọ funfun ni on fẹ, ṣugbọn Ọba fi dudu fun on, o si sọ fun B'ọlọrunkopani wipe ki o jẹki wọn ṣe paṣiparọ, ni B'ọbakopani ba gba aṣọ funfun ti B'ọlọrunkopani ba gba aṣọ dudu.

Bi nwọn si ti rin siwaju diẹ ni wọn ri ti Ọfa ba B'ọbakopani wọn ko si mọ ibiti Ọfa na ti wa, ni eṣẹkẹṣẹ ni o si ku. Nigbati B'ọlọrun kopani ri bẹ o si sare tọ Ọba lọ, o si sọ bi gbogbo rẹ ti ri fun Ọba ati bi ekeji rẹ ti ṣe ku nigbati wọn nrin lọ ninu igbo.

Esi ti Ọba fun Bọlọrunkopani ni wipe, otitọ ni orukọ rẹ, bi Ọlọrun ko ba pani, ko si ẹniti o le pani, Ọba si da ile rẹ si meji ati ọna rẹ si meji, o si fun ọkunrin ti orukọ rẹ njẹ Bọlọrun ko pani e n i a ko le pani Mo dupẹ lọwọ Olotu, Ọkọ ọba ko ni sa yin lẹsẹ o, Ọlọrun ko ni doju ti awa Ọmọ Ẹgbẹ na o, iwaju ni ọpa ẹbiti nre si iwaju ni gbogbo wa yio ma lọ o Amin. o digba kan na.

## Awon omo Egbe Majeobaje



Awọn ti o mbẹ ninu aworan yi ni awọn ti a yan lati lọ ṣe Igbimọ na, orukọ wọn ni wọnyi:- O bẹrẹ lati ọwọ osi, Ọgbẹni Deland lati ilẹ Ghana, Omidan Dokita P. R. K. Nicol lati ilu Saro, J. G. Anthonio lati Ghana ati Dokita F. Aglward ọmọ ẹgbẹ F. A. O.

## Owe Ile Yoruba

LATI ỌWỌ:- ISIAKA. [NO. 144, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE]

Asọrọ kelẹ boju wo gbẹ, igbẹ ki ro, ẹniti a ba sọ fun ni ro ni kiri.

Atẹlẹwọ ẹni ki tan ẹni jẹ. Bi a o ku iṣe ko tan. Didun tan ninu aṣọ ogoje ta da, ti enia mẹfa nwo. Bi a ko ba tọ ọ k ọ lobinrin na, a ki wa Aya rẹ.

## Kini omo nipa Naijiria?

(1) Darukọ Titi (Street) ti ogun ju lọ ni Igboro Ilu Eko? (Opopo)
(2) Darukọ iwe Irohin lede oyinbo ti a da silẹ ninu oṣu September ọdun ti o kọja
(3) Tani ọmọ Naijiria ti o kọ lọ si ilu Oyinbo fun itọju ti o si ku si ọhun lai pẹ yi.
(4) Kini ẹsin ọrọ Naijiria, wi ki n,gbọ?
(5) Darukọ siga meji ti ile iṣe Ẹ g b ẹ Nigerian Tobacco Company nṣe?
(6) Tani Alagbọran dun fun bi a tiṣe nsun owo na fun Ijọba Alapap-ṣe Naijiria
(7) Ọdun wo ni a bi Uthman dan Fodio
(8) Ọdun wo ni wọn da ẹgbẹ Royal Niger Company silẹ
(9) A Da gbogbo awọn eru duro ni ilu Sierra Leone, wọn si kuro loko eru lọdun – – –
(10) Tani Olori alatako ni ile asofin Ijọba apapọ Naijiria
(11) Nigbawo ni Uthman dan Fodio ku?

## Egbe titun miran tunde

EKO:. Awọn ẹgbẹ oṣelu titun miran ṣẹṣẹ bẹrẹ ti nwọn npe orukọ wọn ni ẹgbẹ Awolọwọ kekeke (Awo's National-Movement). Ẹniti ọjọ ori rẹ koiti to ọdun mẹrindinlogun ko le wọ ẹgbẹ na.

Awọn ohun ti ẹgbẹ na fẹ lati ma ṣe ni (a) Lati ma ṣe alaye awọn ohun ti Awo-olowo nfẹ. (b) Lati ma yanju ede koyede larin awọn. ẹgbẹ (c) Lati tun bo kọ awọn ọmọ ẹgbẹ lẹ kọ kun eko wọn. Awo lọwọ si tun ti fi asẹ si ẹgbẹ na ibiti ao g b e ti mase ipade ni No 12, Oluwọle St, Lagos.



# Bi Owo Eru tise bere ni Atete ko se

LATI ỌWỌ:- LATIFU BABALỌLA
(Akowe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye)

Nilẹ oke, siwaju ki Ijọba Gẹsi to bẹrẹ, gbogbo wọn lo nalu ẹru, bi nwọn ba lọ si ogun, nwọn nmu ẹru, bo wa silẹ, idi rẹ ti nwọn se nmu ẹru bayi nipe, ki nwọn ba le ri ẹniti yio ma roko fun wọn ati lati ma ṣiṣẹ miran pẹlu.

Nigbani, ko si owo, beni nwọn ko mọ ohun ti nwọn npe ni owo, de ipo ti nwọn o fi ma gba owo ori, iba ohun ti enia mọ lasiko na ni dakia, gẹgẹbi, ọpọlọpọ ẹran, ẹsin, adie, tolotolo, ati malu. Ayafi igbati awọn ẹlẹsin Aguda de si ilu Eko ti o ko ọti Agba, ewe taba, oriṣiriṣi aṣọ aran ẹtu ibọn iyọ ati ọpọ awọn nkan miran ni awọn ara igbani ma fi ṣe pasiparọ fun ẹru. Iru ipo yi ni awọn ara Eko ati awọn Oyinbo Agudu wa pẹlu ara wọn, bayi si ni owo ẹru sẹ bẹrẹ, nigbati ọsẹ ni awọn oyinbo Aguda lọ ko owo ẹyọ de iru eyiti nwọn nlo, awọn kora ni erekusu Asia, lati inu okun pasifiki (pacific) ninu erekuṣu Phillipine ni nwọn ti ko owo ẹyọ na jade, awọn oyinbo Aguda yi ni nwọn kọkọ jẹki a mọ ohun ti awọn npe ni owo (Potugese ati Spanish) Diẹ ninu awọn ẹya Gẹsi paapa nilẹ Amẹrika dapọ mọ awọn Agudu nwọn yi, nwọn lọ ko eru ni ọpọku ọyọku nilu Eko nwọn si lọ ko nwọn da sinu oko Ireke ati oko taba nilẹ Amẹrika. Lati igba na ni owe ẹyọ ti bẹrẹ si tan kakiri ilẹ Yoruba bi Ọyọ Abẹokuta, Ibadan, Ilesha, Ondo, Ọwọ, Ijebu, ati ni Ifẹ. Nigbati ẹru kan ba fẹ di omnira o ni lati san owo ori rẹ, ni akokọ bayi ni owo ẹru tisẹ bẹrẹ. Iru ipo bayi ni awọn enia dudu ilẹ Aguda ati nilẹ Yoruba wa fun nkan bi odun gbọrọ nigbati o Ịma fi to ọdun 1760 iye awọn ẹru ti awọn Aguda wa soda lọ silẹ Amẹrika ko sẹ fẹnu so, Eo tun ma gbọ bi nwọn ti se da owo ẹru na duro ati awọn ẹgbẹ ti o kọkọ sọrọ nipa rẹ lọsẹ to mbọ, Oluwa ko ṣọ wa di ọjọ mejọ. Amin.

## Akiyesi fun gbogbo awon Omo Ilu Omupo

Eyi ni lati sọ fun gbogbo Ọmọ Ilu Omupo ni Ọkunrin ati Obinrin ati Ọmọde ati Agba ni Ilẹ ati ni Ibi gbogbo ti Ọmọ Omupo ba wa pe Asiko gbigbe Iyawo Ilu Omupo ti bere lati Ọjọ Kini Osu Kẹwa Ọdun yi (Ist Oct, 1961-

Gegẹbi Ofin Ilu Omupo ti Ọdun 1957, Igbe yawo tabi Ifomo foKo ko Gbọdọ peju ọjọ Kokanlelogbọn Oṣu Kini Ọdun lọ (31st Jan. 1962)

Ki a mase ri eniti yio ru ofin yi o. Ki Ọlorun se gbogbo awọn Iyawo odunni ni Alabiyamọ, Amin.

R. A. ỌLAOTI

# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba eda ọ lamu, bi airọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi aitisẹsẹ lo nyọọ ẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiyẹ rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọko bẹrẹ. Ki o si tun ẹna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni ọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MOLEYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA

# Egbe Buruku a ma ba iwa rere je

Lati Ọwọ:- KARIMU LAWAL
Nọ. 42 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Inu mi yio dun bi Olotu ba gba mi laye ninu Iwe rẹ oloyin momọ lati le fi itan kekere yi si awọn ẹgbẹ mi leti itan na niyi. Ni igba kan Baba yi wa, o bi ọmọ meji awọn ọmọ mejeji yi jẹ Ọkunrin ekini a ma jẹ Ọlasunkanmi ekeji ama jẹ Temilade. Ọwa di ni ọjọ kan baba wọn lọ si a jo o si fi awọn ọmọ rẹ silẹ lọ.

Ekini ti orukọ rẹ njẹ Lasunkanmi sọ fun aburo rẹ wipe ko jẹ ki awọn jọlọ si Abule keji wọn si gbera. Nigbati wọn de ibẹtan nwọn ba ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Roro, Roro yi jọ Ọkunrin kan ti Ọlọrun se ọla fun pupọ osi gba wọn mọra nitori nwọn jẹ alejo ni Ilu rẹ nigbati ẹgbọn ri wipe ibẹ dara pupọ oni ki aburo on jeki awọn lọ ko gbogbo aisiki on wab nigbati o de ile o ba baba rẹ ni ile. Osi sọ fun baba rẹ wipe ki ojọwọ ki o fun on ni iba ogun ti on Baba rẹ si sọ wipe kilode oni ko si nkankan rara afi bi oba fun on ni ogun ti on Baba rẹ si fun. O kọ ri si ọna ibi ti o ti wa aburo rẹ si nwo ko sọ ọrọ kankan ojo ko ti baba rẹ koto jọ koto Oṣu ọmọ buruku yi ti na gbogbo ogun rẹ lai ṣe iṣẹ kankan si rara ebi wa bẹrẹ si pa oni kini on kan bayi ebini ọjọ wo ni on ti npa kori omi mu, debi pe o njẹun o wa pada lọ si ọdọ Baba rẹ o bẹ rẹ si bẹ.

Baba rẹ ko gba ẹbẹ Nigbati o ya baba rẹ gba pada o si dari ẹsẹ rẹ ji njẹ ẹgbẹ mi eyi dara bi? ẹma se ko Ẹgbẹ buburu, Ẹgbẹ buburu a ma ba iwa rere enia jẹ ni Eko.

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




OLUBORI EGBOGI "IKỌ

THIOLYPTINE

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbi-rọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni Thiolyptine ojulowo haunhaun, atimatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ lile, Ikọ' ti o ma mu enia tu kẹlẹbe nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pọlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi Thiolyptine yi wo,Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.

Bere egbogi yi ati awọn oriṣiriṣi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

Price 10/6 Postage 3/-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA
ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 9)

Lati Ọwọ:- Simeon Adegoke Fatoki

Ipo kipo ti ẹ le wa ẹma ṣe gbagbe Ọlọrun Ẹlẹda yin Ẹlomiran nwa ki on ti lẹ wa ni iru ipo ti yin ju ki o ku lọ, ṣugbọn a ko ṣe tirẹ bẹ. Mo fẹ ki ẹ dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ore rẹ lori yin, ati pe bi emi yio ṣe ma nlọ yi, ibikibi ti mo ba wa, emi yio ma ranti yin. Emi ko si ni gbagbe lai bi ese yọ mi si yi, Ọlọrun ko dabo bo yin o. Amin. O digba o"

Nigbati mo pari ọrọ mi tan, gbogbo wọn fi ohun kan ke pe "O digba o." Ọlọrun yio sọ ẹ, yio dẹ bukun ọ, Ọlọrun ko ni pada lẹhin rẹ ni gbogbo ibikibi ti o ba nlọ o, o digba o, Ẹ ki awọn ara ile pata o. Bayi ni mo ṣe, ti mo fi ilu Afọju yi silẹ, ti mo si tun nba irin ajo mi lọ, mo fẹ ki ẹnyin Onkawe yi mọ pe, o ti di oṣu kan ati ọ j ọ kọkanlelogun ti mo ti fi ile silẹ. Mo si lero pe ko j i n a pupọ mọ ti emi yio fi de ibi ti ogbologbo Agbọnrin oniwo meje yi sọ fun mi pe, emi yio ri ọna ibiti wọn ti nlu ilu, ki nto wa lọ kan ajule Ọrun nibiti a o si fi ọgbọn fun mi.

Mo sa bẹrẹ si rin lọ, mo si ngbadun ara mi niwọnba igbadun ti o yẹ ọmọ-luwabi, bi mo se nṣe gbogbo iwọnyi emi ko tilẹ gbagbe Ọlọrun Ọba mi rara, ṣe ni mo nke pe lọsan ati loru pe ki o ṣe atilẹhin fun mi ki o ma si se ti mi loju ninu irin ajo mi yi.

Nigbati o di owurọ ọjọ kẹrin ti mo ti fi ilu afọju yi silẹ nibiti Aditi ti nṣe Ọba wọn, ni mo dede ṣe alabapade awọn omọde binrin meje kan ti nwọn nrin ẹrin kiri ọjọ aiye wọn. Ẹnu ya mi pupọ lati ri awọn obinrin yi, nitoripe wọn dara pupọ, nibiyi ni ori mi ti yi ti mo si gbagbe Iyawo mi ti mo fi silẹ ni ile, mo ni ero pe ti mo bạ pe awọn wọnyi ti mo ba si fi ikan ninu wọn se aya ki ba ma kuku dara pupọ o, ṣugbọn nibiti mo ti nro eyi lọwọ ni mo ri ti ọkunrin arẹwa k a n yọ si mi, o dabi angẹli, o si duro ni iwaju mi o ni Iwọ ọmọ enia, emi ti mọ ero inu rẹ mo si ti mọ ohun ti o fẹ ṣe, ṣugbọn maṣe se bẹ rara nitoripe iya ni awọn ọmọbinrin yi njẹ ni ibi yi, Ọlọrun lo fi wọn sibi ki wọn ma rẹrin titi ọjọ aiye wọn. Nigbati ọkunrin yi pari ọrọ rẹ tan, mo wo loju mo si bere lọwọ rẹ, mo ni jọwọ enia Ọlọrun ma sai sọ fun mi ohun ti awọn arẹwa obinrin yi kuku se to bayi?.


## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWỌ FUN AWON ABIYAMỌ

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ti a se ni ase pe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pelu idaniloju fun Awọn ise ribi ribi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara fun igbona, ikọ, otutu A i p e r i, Osi Ọmọde, jedijedi, kokoro ori Ọmọde. O dara fun omọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ọmọde ko ma nnun fọnfọn O mu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn omode e sinjeki awọn omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Ẹnyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin letipe MOGABYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko ṣe mani fun awon Ọmode I j a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni le itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re jẹ 2-6d Igo nla jẹ 4-6d

LILO RẸ:- Sibi kekere lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A, K. KARIMU ANJOLA & BROS

6 Balogun Street, Lagos Nigeria, Phone 22515

West 34, Docemu Street, Lagos, Phone 24247





# Isedale Yoruba.

Lati Ọwọ:- SHITTU FAGBEMI

No 32 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

Awọn Enia ti a npe ni Yoruba je Ẹya Pataki ni Ilẹ Naijiria, Nwọn pọ, nwọn to Igba Ọke Enia (4,000,000) nwọn si pin si Orisirisi ẹya kekeke Gẹgẹbi Egba, Ifẹ Ijẹbu Ọyọ, Owu, Ijẹsha, Ekiti, Ondo, ati Eko (ni igba laila) Odo Ọya (River Niger) ni nse A ala ilẹ wọn ni Iha Ariwa (North) Omi Ọsa ni Iha Gusu (Saoth) Ilẹ awọn Ibini ni Iha Ila—Orun ati Ilẹ awọn Idahọmi ni Iha Iwọ Orun, Awọn enia wọnyi ki ise Ibilẹ Ilu Naijiria ati Ipinlẹsẹ wa, nwọn kuro ni ilu ati ilẹ wọn lati wa te Ile Yoruba do ni Ilẹ Naijiria, Nibo ni awọn enia na ti wa. Eyi ni Ibere ti oyẹ ki abere, Idahun rẹ farasin diẹ nitori awọn enia ti a npe ni Yoruba ko tete ni akọsilẹ nipa Isẹdalẹ wọn. Sibẹsibẹ itan sọ fun wa ni Orisirisi ọna pe awọn enia na ki ise Ibilẹ Naijiria lati Ipilẹsẹ wa

Ni agbegbe ilẹ Egypt ni Ila Orun ni nwọn ti wa, ọpọlọpọ Isesi wọn ni ojọ ti awọn ara Egypt tabi Ila Orun.

Bi nwọn ti ṣe gbẹ Okuta Alarabara ni Ile—Ifẹ ati bi nwọn ti se nsin oku wọn jo bi awọn ara Egypt.

E o si ma ri iyoku ka ni ọsẹ tombọ, Lẹkan si mo gba ẹnyin Ọmọ ilẹ iwe Lọkunrin Lobinrin ni amọran pe ki ẹma ka Irohin Imọlẹ Lọsẹsẹ MODUPẸ O.

# Wole-wode Oba nile Ghana



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ti o ga agborun ni Major Michael Otu, ara ilẹ Ghana ti o nṣe wọle-wọde fun Ọba Elisabeth nigbati o lọ bẹ ilẹ Ghana wo.

O ti kọkọ lọ ti oju kan Ọba na ninu afin rẹ, ṣugbọn nigbati o npada bọ lati afin ni ojo bẹrẹ.

Major Otu jẹ Jagun-Jagun, o si ti ṣe wọle-wọde fun Duke ọkọ Ọba Gẹsi nigbati on nikan fi lọ bẹ ilẹ awọn Aganyin wo.

IROHIN IMỌLẸ DARABA

Ẹ MA K A W E IROHIN IMỌLẸ NIGBAGBOGBO KI Ẹ SI MA POLOWO ỌJA YIN SINU RẸ.



## Omode keke-re kan hu iwo lori

Omode ti a nwo ninu aworan yi ti o hu iwo lori rẹ, jẹ ẹkan ninu awọn O m ọ ilẹ Aganyin ti o dira ijo, ti o si ko ilu si ẹhin ati lọ pade Ọba binrin ti ilu Gesi. Imura rẹ yi jẹ gẹgẹbi awọn ọmọ ọba ilẹ Aganyin ti ṣe ọṣọ, o si jẹ ọmọba Omahere Akwapin

O fi oriṣiriṣi iyẹ ṣe ṣe ọṣọ ori ati iwo ẹran Malu.

Gbogbo awọn oworan lo nwo O m ọ na tiyanu-tiyanu.



## Jagun-Jgun Ibile Ghana, ki Oba kabo.

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni ara ilẹ G h a n a kan ti o mura gẹgẹbi awọn Jagun Jagun ilẹ Ghana ṣiwaju ki awọn Oyinbo o de, ẹ o ri bi o ti duro gẹgẹbi awọn ti nki ọba Pẹrẹmpẹ nigba atijọ. A gbọ wipe ọkọ Ọba Oyinbo o duro o nwo awọn Jagun Jagun Ibilẹ Ghana yi, o wipe imura awọn ọmọ Ogun na fi ara jọ ti awọn akọni ilẹ Rome nigba atijọ.


## Iwo ha Nfe Igbega bi?

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, ti ko le mọ ile iṣẹ wa ni Mushin, ni aṣẹ kọ awọn apakan ninu ọja wa si Nomba 16 Bamgbose Street Lagos, ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ọja wa ni Eko ki o ma lọ sibẹ.

TURARI AJẸBIDAN AGBABIETU

Turari yi ko ni ẹgbẹ akose fun awọn ajẹ ni, ti o ba loo iwọ ko ni mọ a i t a ọja. Adura rẹ yio si ma a gba awọn enia buruku aiye ko tilẹ ni lagbara lori rẹ onṣiṣẹ to igba ọna (200 ways) fun igbega ọmọ enia ni A i y e . (Pangolo 10/6d)

MANANGRE (J. O. SHOYINKA.) c/o IROHINIMOLẸ
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.



BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIK TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹE-emi (breath) inu ko ba gunlẹ daradara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJE" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja ọgbọn ọ d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria
Phone: 22878 (Ọja ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## OBERE LATI OJU EWE KEFA.

Dajudaju awọn olore wa yi ti mọ wipe ẹnikẹni ko fi Iṣẹ aburu yi ran e, nitorina won kosi ni keti si isọkusọ ati iwa asorun iwaju po mọ ti ipakọ ti iwọ nsọ jade lẹnu yi. Nipari ọrọ mi, mo fi irẹlẹ kesi ẹgbẹ N. P. C. ti Alhaji Ojọmu nse ọkan ninu Asiwaju ni Ilẹ Igbomina ki wọn bẹrẹ si se akiyesi iwa tẹmbẹlẹkun ti ọkan ninu ẹgbẹ won nhu, ki wọn si ma woye awọn to ngo ọwọ Irẹpọ sẹhin larin Ilu. Modupẹ lọwọ Olotu aye ti ẹ gba mi Ajinde ara yio ma je fun gbogbo wa Amin.

E mi ni A. Ariyayọ (Ọmọ Sisa ekun to jokọ)

## OBERE LATI OJU EWE KEFA.

Kise oja ilu kankan ninu wa, gbogbo ilu tinjẹ ẹku Mẹsẹsan oro loni oja na. Ni ẹrugbẹlẹ ni wọn ti nna Ọja na tẹlẹ, sugbọn nigbati Ogun ẹgbintin de, ti won nko awọn ọja, ni gbogbo ilu mẹsẹsan tinjẹ Oro base ipade pe ki oja na lọsi ilu ti Ọba ba wa, Oke-Ọja sini Ọba wa, Nigbana, wọn sigbe Ọja Oro yi si Oke Ọla Oro. Ṣugbọn nigbati awọn Ọtun Oro mba Ọba wa ja, Ala-Iyeluwa Ọba Abọlaji Ọlasọpe II, fun owo ori didu, wọn lọdi rigimọ Ọba bibaja yi mọ awọn ilu toku, gẹgẹ bi ẹyin na ti ṣe mọ wọn ti wọn ba fẹ ba ilu kan ja, wọn yio lọ ba awọn ilu toku, wọn awa kọ ọgbọn ẹrọ bọ wọn ninu. Ija awade, nipa bayi ija Ọba ti awi yi pọ pupọ, nigbati wọn kori Ọba yi bọ kuro lori oye, ni wọn ba gbe Ọja na kuro ni Oke-Ọla lọsi Ọtun Oro. Ọtẹ Ọba Bọlaji lo gbe ọja yi lọsi Ọtun Oro, Ọgbọn ẹrọ na sini wọn fi gba Ọja na mọra. Ṣugbọn nigbati adibo Igbimọ Ijọba ibilẹ (Oro District Council) ti awa ẹgbẹ Olomi (N. P. C. ) si wọle, awọn wa pinnu pe ki Ọja wa, wa ni gedegbe laifara ti ilu kankan atipe yio mu Ogo pẹlu iyi nla ba Oro, yatọsi ibi to wa tẹlẹ.

KO ITI PARI.

## Nigerian Ports Authority

VACANCY-WORKS SUPERVISOR-DIVING INSTRUCTOR

Applications are invited from suitably qualified candidates for the post of Works Supervisor - Diving Instructor in the Engineering Department of the Authority.

QUALIFICATION:

Preference will be given to persons who have been trained as a diver by Siebe Gorman, or Royal Navy.

DUTIES:

The successful candidate should be able to demonstrate from an observation tank and instruct indigenous staff on diving operations, such as, placing and firing procedure in the use of underwater explosives, underwater air bolt firing, underwater flame cutting, welding, drilling, concrete placing, fitting, carpentry and other craftsman work required of a fully competent diver.

SALARY:

Scale 5: £1,350 x 56 - £1,686, plus £300 per annum, overseas allowance where applicable, in addition to which there will be a diving allowance of £75 per annum.

METHOD OF APPLICATION:

Application forms are obtainable from the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, Apapa Dockyard, and should be completed and returned so as to reach him not later than 15th of December, 1961. Candidates in the service of the Government or a Corporation must submit their applications through their Heads of Departments who will forward same to the Personnel Manager along with Confidential Reports. Persons without requisite qualification and experience need not apply.

N. P. A. Notice No. 648
14th November, 1961.

*BAYO KEHINDE*
Secretary to the Authority

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN PE NI:-

# RICHALET FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Robi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ, ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIK Ejẹ ti wọn si nta kakiri ni ọw pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ n ko di owo, Iyẹn ṣe ewọ awa ki awọn egbogi bawọn yẹn rara ti awọn npot ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti a ntaoṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, F a r a n se, ati ti awọn Tatabulu si Itali jẹ. Mọ daju pe bi Ejẹ ara ko ba mọ daradara awọn amọdi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ Lakuregbe, orişirişi Inarun Ojuşişu tabi didun JẹdiJẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Aya didun Itanpara, ekuru lara.

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apo ile itọ ẹhin didun tabi Ibadi riro pẹlu egbogi Rişalcti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu E j ẹ ara patapata yio si fọ ejẹ ara rẹ mọ tonitoni pẹlu Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹ l o m i r a n pẹlu nigbakugba.

Bere egbogi yi ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## Akiyesi Pataki

**Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!**

SENGOVAN: Tablets: Je ajidewe fun awọn agbalagba ati Ilera gẹgẹbi ọmọkunrin.

SENGOVAN: Jẹ ọkan pataki ti a şe iwadi ni ilu Oke-re ni ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Onişegun Arẹmọ ti ilu Western Germany. Fun awọn ẹniti ọjọ ori rẹ to Ogoji si Ọgọrin ọdun (40: 80 years.)

SENGOVAN: Jẹ ogun ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn Agbalagba Ilu Jamani, ki a to şe amuwa rẹ si ilu Naijiria. Ajẹbidan ni ogun yi Irohin ko to afojuba.

Bere. A o ri lọwọ awọn Onişegun (Doctors) Naijiria tabi lọwọ Alagba Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES 26, BISHOP STREET LAGOS. PHONE: 23745. DIRECTION: 1 to 2 Pills is sufficient for your constitution, if so do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985. Olotu E. A. Adeniji 51, Tejuosho Street, Suru-Lere, YABA.